# IWA IBAJẸ TO WA NI ILE AIYE WA YI

### Lati Ọwọ Ẹfufu – Lẹlẹ Eko

Ẹnyin ọmọ enia ẹku iyalẹta ode oni. Ẹ si ku aṣẹhinde Kabiyesi nyin Ọba Adele ti Eko Mo ba nyin kẹdun nigbati a gba kuro lọwọ nyin lode aiye. Niwọn ọsẹ melo kan to kọja Emi Ẹfufu Lẹlẹ so ninu iṣipaya mi pe ki awọn alagbara aiye ma ṣọra nitori bi mo ba tẹ doje mi bọ oko gbogbo koriko aiye yo mọ Oko to ku fun koriko yo fẹrẹ di ẹgalẹ nitori idoje mi mu kọja ala Bẹẹi ti mo ba tẹ igba mi bọ okun Gbogbo omi yo fẹrẹ gbẹ fun ọjọ meji Bakanna ni bi mo ba bẹ aiye wo Jinijini yo ba ọmọ enia fun iwa ibi to wa lrain wọn.

Ohun to jẹ ẹrin fun mi ni pe awọn tilẹ npe ara nwọn ni ọlọgbọn ati amoye enia. Nwọn ko mọ pe bi ọlọgbọn ti nku bẹni asiwere ati ẹranko enia nṣegbe. Nwọn nfi ọrọ ati ohun ini wọn silẹ tun ẹlomiran Emi Ẹfufu Lẹlẹ nwo nwọn nigbati wọn nronu pe ki ile ati ọna wọn wa titi lai ati ibujoko nwọn lati irandiran. Ohun gbogbo ti nwọn ba ni ile nwọn sọ ohun ini wọn nipa oruko ara wọn.

Nwọn tilẹ gbagbe wipe enia to wa ninu ọla ati iyi ko duro pẹ titi wọn tilẹ dabi awọn ẹranko to nṣegbe ninu igbẹ. Awọn ọmọ nwọn tilẹ nireti pe ọna baba wọn tọ. Ki a ma ri Emi Ẹfufu Lẹlẹ tilẹ nwo asiṣe wọn ati ireti nwọn bi iwa omugọ.

Awọn iṣipaya ti a fi han mi nipa iwa awọn ọlọgbọn, ọlọla ati ọlọrọ nipa bi agun tan li a tẹ wọn si nu sareoku Iku yio jẹ aṣẹ lara wọn Aṣẹhin aṣẹhinbọ ẹwa nwọn yo parun kuro lori ile nigbati isa-oku yo jẹ ibugbe wọn.

Nigbati mo wo iye awọn enia to nkọja lọ si ile aiyeraiye. Emi Ẹfufu Lẹlẹ bere lọwọ awọn a ba ni damọran Ọrun idi ti awọn ogunlọgọ enia wọnyi fi nre kọja lọ si ilu ọrun. Ohun ti mo ri ni pe Olodumare ti wipe ọgọfa ọdun ni ileri ọjọ ọmọ enia ṣugbọn nigbati oju kokoro ati iwa wọbia ati wọmibiliti pọ lerin nwọn.

A ke ọjọ ọmọ enia kuro. Ọpọ ninu awọn ti npe ara wọn ni ọlọla ko tilẹ mọ bi ati ẹrin. Nwọn nrin bi igala ninu oko. Oju nkan wọn lati jẹ aiye kiakia. Bi nwọn ti njẹ girigiri yi bẹ ni a si npe wọn loke lọhun fun isiro igbe aiye ọnikọkan wọn.

Emi Ẹfufu lẹlẹ duro lori ote ile ẹrin ọba Adele II nigbati nwọn nsin oku ọba nla yi. Bi awọn ogunlọgọ aimoye enia wọn yi siwa wo ran oku Ọba yi. Mo ri awọn kan tiwọn wọ aṣọ nla nla ṣugbọn kiẹc Iwa ola ni

o wa ninu wọn. Bi awọn wọnyi ti fikiri ni mo tun ri awọn obirin ti awọn na tun wa ninu aṣọ ẹgọ won ṣugbọn kise Iwa ọmọluwabi to wa ninu won. Eyi nkọ ọmọ enia lẹgbẹ kan mo nwo awon kan ti nwọn ṣe ri kodo wipe ojẹ ọba yi lọ ni yẹn? Motun ri awọn kan ti won sọrọrun ọba bi awon kan ti nwon wipe ojuṣ ju enia ṣugbọn ngbati mowo inu ile yi mo ri awọn ẹni iru ju

Nihin nino kẹdun fun wọn nitori wọn wipe bawo ni ọla wọn yio tiri? Mo ri awọn iru enia wọnyi ninu pe ki wọn ma banujẹ di alaini ire ti Nitorina Emi ẹfufu lẹlẹ yio gba ọrọ wọn wo niwaju itẹ ỌGA OGO Kiki ki wọn fi ọkan wọn sin Ọlọrun Ẹleda wọn

Ninu iwe iṣipaya mi yi mo ni lati jade ọtọ si awọn ti nṣe ẹalegale wipe ko si bi ti awọn ko to.

Ọjọ ibẹwo Emi Ẹfufu Lẹlẹ de si ode aiye. Ibẹwo mi na ko ju wipe lati yẹ iṣẹ awọn ọlọla wo. Awọn to nko ọrọ jọ ti ki ise ni pa ọna ododo. Awọn ti ngba ile onile lai ro ẹhin ọla rẹ wo. Ibẹwo mi larin awon onipo nla ti wọn ko ranti awọn ti o wa ni iṣalẹ.

Emi Ẹfufu Lẹlẹ de inu aiye pẹlu ọwọ agbara mi Emi nkilọ fun gbogbo oniruru iwa. Yala wọn jẹ oselu tabi onisowo yala akọwe tabi alaikọwe. Bi ẹniti njẹun ni tabi ẹniti ebi npa a Emi Ẹfufu Lẹlẹ yo woiṣẹ nyin. Eniti ko ba tẹ iwọn ha! ha!! ha! ! ya! ya!! ya!!! Odi ọwọ nyin. Emi Ẹfufu Lẹlẹ fẹ lọ bẹ ihala orun wo. Rere runlẹ nibẹ. Wo emi yio de igun mẹrin ile yi. Emi yio si so ohun wọn ni ti mo ba ri. Ẹfufu Lẹlẹ rele o!

Kasifo, saijumọ, Odi ar!!!

Emi ni Ẹfufu Lẹlẹ.

# Ayọrunbọ Ati Panpalaso

### Apa Kẹrin

LATI ỌWỌ:— J. O. SHOYINKA

Lọjọ meje lori ti ẹlẹmi ko ba gba a, ngo jọba Ori Eru, gbogbo wọn ni Kabiyesi! Kabiyesi!! Kabiyesi!!! Alaṣẹ ibikeji Oriṣa.

**IROHIN KAN ỌBA ATI IJOYE AIBALẸ ỌKAN DE**

Nigbati Ọba gbọ ohun ti o ṣẹlẹ yi, o pe awọn ẹmẹ wa rẹ jọ, o ni ẹ gbọ ohun ti Ayuorunbọ wi? Nwọn ni ko ri şişẹ, ko laiṣe, jijade ni o yẹ ki on jade kuro larin ilu, nitoripe iku ya ju ẹṣin lọ, Ọba ronu titi ti o ni, mo gbọ mo durẹ fun iyanju ti o gba mi, bi Ọlọrun ko ba kọ iṣẹ ẹru re ngo jade kuro larin ilu ki Ayuorunbọ to le mi jade O pe gbogbo ẹbi ati ẹmẹwa rẹ jọ o ni ẹnyin enia mi, gbogbo nyin ni mo ki, ẹ ṣe ẹ ku aroti mo ti ọjọba lori nyin ti pọ igba pada, mo ni lati fi agbara fi ilẹ Baba mi silẹ lati lọ ṣe atipo ni ilẹ ibomiran, ori ade wa dori fila mo gba f'Ọlọrun, mo gba b.ẹ.

Ni ọla ẹgo kuro ni ilu pẹlu awọn ọmọ mi ati awọn aya mi ṣugbọn ti mo ba lọ, ẹ ma gbagbe mi, ẹ ma fi ọrọ mi sinu adura ki nle pada si ori itẹ Baba mi, mo fẹ ki ẹ fi tenu yi kọ ọgbọn, mo si fẹ tun fi ọrọ yi gba yin ni iyanju ki ẹ tẹti ki ẹ gbọ Ẹsan ko gbogun e ṣọra Ẹsan ko gbogun, ẹ ṣọra gidigidi, Ẹsan ko le ṣalai ke, Ẹni huwa ibi, o pẹ o ya yo jere rẹ Airoju a ba ika tile tọna, Alẹ ika ki si i dara.

Ọmọ ika, aku, le iku a dahoro, Ẹtọju iwa nyin, ẹsan kii ṣalai ke. Ẹsan ko gbogun o"

Bi o ti pari ọrọ rẹ gbogbo awọn ti o rọgba yi ka, bu sẹkun, nwọn bẹrẹ si sunkun ki kuro, tayi ni Ọba ori eru fi jade kuro larin ilu, nitori o jade, ṣugbọn awọn mọ ẹhin rẹ ko gbagbe rẹ.

AYỌRUNBỌ JỌBA

Okiki ti kan yi gbogbo ilu ti ngbegbe rẹ ka pe, Ayọrunbọ ni yio jọba. Ali kiamọsa awọn adifa ilu ti da ifa nwọn ni, Ayọrunbọ ni ifa mu, bi ifa mo nko? tani jẹ sọ abẹ ni iko? Adifa wo lo le la ẹnu agbari rẹ so pe, on kọ ni ifa mu. Ni kukuru nigbati ọjọ keje pe, o fi ara rẹ jọba, nwọn ise, nwọn nsọ, gbogbo rẹ ndun yungba, awọn ọmọ ẹhin Ọba ori Eru nwa ọna lati tun fi mu Ayọrunbọ. nwọn ndite yi labẹlẹ ni

Ayọrunbọ fi ara rẹ jọba Ori Eru, ṣugbọn awọn ọmọ ẹhin ọba ti o le kuro lori itẹ, nwa ọna lati muu.

Ayuorunbọ fi awọn ẹmẹwa rẹ joye, Lo ni kun to, ko si ni dun to, ti ngo ba isọ ruko oloye kọkan ati iri si wọn, Oruko Oloye kini ni LAKULAKE Ogbọju ẹdẹ ni iṣe, olagbara pupọ, komọ ẹgun pupọ afi ayajọ. Gbogbo ilu ti ọbẹru rẹ ni torope ki ro ki fọ Ohunkohun ti yio ba se, inu

Ao Oju Ewe Karun

REMAIN YOUNG 100 YEARS
Details:– Add. C. T. Hospitals (R. Y.) Azad Market, Delhi, 6, India.

# IWE SI OLOTU

## Mo kan Saara si Olotu

Olotu eti awọn alaba ṣiṣẹ pọ rẹ mo si dupẹ pupọ lori idajọ Baba wa Oloye Awol wọ ti ẹ jẹ ki awa Ọmọ ilẹ ẹkọ ti ko ti ile ka iwe lede Oyinbo nri ka ninu we nyin Oloyinmọmọ "Irohin Imọlẹ." Eleyi ṣi ji ko jẹ ibanujẹ fun ẹdun ọkan mi nigbati a ko le ri i e Irohin ti yio fun wa ni ẹkunrẹrẹ idajọ na lede Yoruba.

Ṣugbọn mi ko mọ gẹgẹbi ọkan mi d i nigbati mo ri iwe Irohin Im le ti ọjọ kẹtaia Oṣu keji Ọdun yi ti mo ri ka pe ẹkun rere idajọ na yo jade ni ọjọ kejo na. Ako si ti ṣọ fun gbogbo ọrẹ mi ati pe ,nu awọn Ẹlẹgbẹ mi si dun pupọ nigbati a r; Irohin na ka ni Owurọ ọjọ keji. Gẹgẹbi Olotu iwe Irohin Imọlẹ ti sọ pe eleyi yio jẹ Ohun Itan lotọ ni yio jẹ ohun itan. Mo si dupẹ gidigidi fun iranlọwọ ti Olotu Irohin Imolẹ ṣe fun awa Ọmo Ile Ẹko ti ko ti lo ka iwe Irohin lede Oyinbo ti o jẹ ki asi nri iwe na ka, Inu wa yio dun bi iwe na ba tete nde ilu wa nigba gbogbo,

Emi ni
Ọlatunde Dauda
Odolẹwu Ijẹbu-Ode

## Ẹ ma Binu, Sa

OLOTU Inu mi yio dun pupọ ti ẹ ba le gba mi laye diẹ ninu gbajumọ iwe irohin Imọlẹ rẹ Aladun lati bẹ Alakoso Ijọba Apapọ Alhaji Abubakar Tafawa Balẹwa pe ki nwọn jọwọ maṣe binu nipa hiho ti awọn ọmọ Naijiria ho lelori nilu Oyinbo nigbati wọn fi lọ sibi ipade Ẹgbẹ Igbimọ Agbaiye (Commonweath Conference).

Ẹ jọwọ Alagba ẹ maṣe binu Agba ti ko ba binu ni ọmọ rẹ pọ, ẹ jọwọ ẹ dari jin awọn ọmọ Naijiria.

Ẹ seun o ẹ ku iṣẹ o.

Olotu mo dupẹ aye ti ẹ gbami Oluwa ko wa pẹlu yin.

Emi ni
Florence Olarewaju
Middlesex England.

## E fi Awo Sile

Ki iṣe pe ki a ma paiwo Awolọwọ kiri ni yio gbe jade tabi i a ma lu ilu kiri ki a si ma ki ni o le san lọwọ eyi tun nda si lọrun ni ti a ba mọ pe a ni ifẹ Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ẹ jẹki a kun fun adura atokan wa ki o le gbe jade wa ba wa ni alafia.

Ọpọlọpọ ninu wa ti o kigbe Awo! Awo!! Awo!!! ni ko ai ifẹ rẹ deiwu, ẹ jeki a simi ajwo rẹ ti a pakiri ki a ss sesi a ko tile fẹ mọ ki awi duro de ibo lati fi gbe jade eleyi ni emi ri pe ole ran wa lọwọ.

Nitori odi ọwọ wao.

Lati Ọwọ,
FATAYI OYERGBA.

## Iwa yi ko dara

Jọwọ gbami ni aiye ninu iwe rẹ Irohin-Imọlẹ akọmọlede ti gbogbo enia ma nka ni ojojumọ ba gbolo awọn ọmọ Nigeria tio wa ni ilu Oyinbo sọrọ lori iṣẹlẹ buruku tio ṣe lalpẹyi nigbati Alakoso Apapọ Ijọba Naijiria. ibẹwo ilu Oyinbo nibiti nwọn tise ṣe ipade kan nibẹ.

Ohun ti o ṣẹlẹ na nipe gbogb wọn ọmọ Naijiria ko ra wọn jọsi ibi itosi ile ti wọn tise ipade na

nigbati Alakoso Naijiria se si de, Awọn bẹrẹsi pariwo le lori ti wọn si nbu pe ki o sare ya fi oloye Awolow silẹ Iwa yi ko da ra lati ma bu Alakoṣo ilẹ wa ni ilu okere Itiju nla ni osi tun jẹ B io tilẹ jẹ pe oluwa nfẹ nka tio ba de iwe ni o yẹ ki wọn han nipa bi nkan ti nlo si ni i ẹ

Ẹ a sare kowe si Alakoṣo na fun idarijin nitori ẹli doju ti loju gbogbo aiye

Emi ni
U, S, A. Bisi Adekoya

## Ogbogbo Nfẹ Atunse

Olotu jọwọ gba mi ni aye diẹ ninu iwe nyin oloyinmọmọ adura mi si nyin ni pe ki Ọlọrun ma ba nyin gbe ki iwe Irohin Imọlẹ na ni itẹsiwaju

ọrọ mi na ni pe mo kesi Olotu Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria Oloye S L Akintọla ki o lo ipo rẹ rere lati kesi Alakoso eto iṣẹ Ijọba Ipinlẹ rẹ lati ba wa mu oju to ilu wa Ogbogbo ni Ijẹbu lati le ba wa ṣe atuuṣe gbogbo ọna ilu na ati awọn nkan miran to yẹ ki Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ṣe fun ilu Ogbogbo nipa eto ilọsiwa ilu na

Inu awa ọmọ ilu Ogbogbo yio dun bi Ijọba Akintọla ba le tete ṣe awọn nkan nwọnyi fun ilu wa nitoripe awọn enia ilu na ki ifi o [illegible] jafara lati san ati pe asi nfẹ awọn nkan ti yio mu ilọsiwaju ba ilu na ao si ma reti Ijọba nyin o

Mo dupẹ pupọ o Olotu

Emi ni
Ọladele Ogunlẹyẹ IJẸBU

The best watch in its class




AJIBỌLA & SON
279, L. E. D B. Shops,
Imman Ligali Street,
Ita Akanji Area,
LAGOS.

Bi O BA NI
**Iwe—Titẹ**
FUN
**Lilo nibi Iṣẹ rẹ tabi orişirişi**
**Iwe itufọ tabi ijade Oku**
ATI
**Iwe Igbeyawo**
KỌWE SI ILE—IṢẸ—ERỌ ITẸ IWE
**Modupẹ Printing Press**
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985, Lagos.
EKETE NI ERỌ-ITEWE WA NHAN
OWO PỌỌKU NI A SI NGBA
IROHIN KO TOAFOJUBA
Dan wa wo lẹkan soso ṣoṣo ko si ri iyato

GBOGBO ARA ILU NKỌ ORIN IYIN ati AYỌ NIPA "DYNAMIREN" TỌNIK



ALE-BI-ELE Egbogi Tọniki Jamọnu titun ti gbogbo a a Ilu Eko ati jakejado Naijiria mọ daju fun Akọ gbara ati Ajẹbidan iṣẹ Rẹ lara Agbalagba Ọkunrin g ogbo'

Bi arẹ ara ba nmu ọ, nigbakugba fun wahala lala şişẹşẹ ti o kọ ie jẹun daradara, tabi ki o male sun dada ọkun lọsan tabi loru tabi awọn iṣan ara rẹ gbogbo ki ṣe fun daradara ti Eemi (Breath) inu ko ba gunlẹ daradara wọn iṣẹ tabi wahala şişe tabi fun awọn ailera gbogbo 'nyin ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja Ọgbọn ọdun o si de adọrin tabi jubẹ lọ. Mo dupẹ "DYNAMIREN' ni egbogi ti e nfẹ lati sọ ara di ọtun patapata anu rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bi ẹ s'i do dada. Ara rẹ yio ma gbe kankan nigbakugba y'Arẹ" nigbakugba yio salọ pẹlu igoọaba-dun ati alafi diro de ọ. Iyẹn daju. Bere Egbogi na ni Ṣọbu: awọn

NIGERIAN- MEDICINE STORE
4, Tinubu Square Lagos

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos.
hone: 22878 Nigeria. (Ọja Ita Faji)
ATI NI AWỌN ṢỌBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY
IBADAN

# Ẹ O Leke Ajipete

Lati Ọwọ LHADJI Y. A. DISU

Ẹ maṣe fi eti si ọrọ asinwin, Ẹ maṣe fi eti si ọrọ kẹnimani Ẹ maṣe fi eti si ọrọ onisọkusọ aronika Ẹ maṣe fi eti si ọrọ onisọndi sọndi Ẹ maṣe fi eti si ọrọ awọn ẹlẹgan Bi ọmọ enia ba ronu jinlẹ yio gba wipe iruiẹ awọn enia bẹ ẹ ti wa lati ọjọ ti alaiye ti da aiye.

Irufẹ wọn ni nwọn sopọnpa gbe ogun ti Anabi Muhanmed, ki ikẹ ati ọla ma a ba a titi lai ai, tobẹ gẹ ẹ ti nwọn fi lẹ e jade ni ilu baba rẹ Mẹkka.

Nipa adura si Ọlorun ati nipa ṣiṣe daada, Ọlọrun Ọba Ogo si da aabo bo o, ko si fun wọn ni agbara lati sọ ọ di akinrindin ko si fun wọn ni agbara lati lu u fi a Ọlọrun ma a nṣe atilẹhin fun olododo eru rẹ ai, ki i si si lẹhin alabosi Ki i si gbe ẹbi fun alare Ki i si gbe are fun ẹ ẹbi.

Gbogbo ẹniti ibi rẹ ko ba pe perepere, ki o pe daadaa bi Anabi, ọrẹ mi, (ki ike ati ọla ma a ba a titi lailai) tabi ti laakaye rẹ ko pe. ti laakaye rẹ so rikodo bi ti o ba burẹwa ni o ma a nsaba ba ọmọlẹkeji rẹ jẹ kaakiri adugbo ati kaakiri ilu.

Doogọ kẹnimani enia tabi enia kikuru bibisi ti ko ba ri iṣẹ kan ṣe tun fẹran lati ma a bi enia ti o ba san ju u lọ, ti iyẹn ko ba fun uu ni okele. Ẹni okele ni awọn ẹlẹ, alapa maṣiṣẹ Onijibiti ni wọn jẹ.

Bi Alhaji Ọmọ-Ọba Abudu Whaid Elias ti jẹ Ọlọrọ to lode toni ati ti Oloye Ọmọ-Ọba Aminu Kosọko ti ẹ Ọlọrọ to lode toni, ẹ ko jẹri wọn ki nwọn ma a ṣe ẹrẹkẹ eebu.

Nwọn bi wọn re. Nwọn si tun ara wọn bi. Nwọn ki iṣe ọle enia. Nwọn ki si ṣe eburẹwa. Bi kẹnimani ati ọlẹ enia ba di ọtẹ, ti o si nra eebi si nyin lara ni o ta o. Ẹ dupẹ fun Ọlorun, ki ẹ ma a gbara ni igbogbo igba Ki ẹ si ni igbagbọ si Edunmare pe, o otọ ni yio leke. Anabi Muhanmed leke awọn ajipete.

Anabi Yisa (Jesu) si leke wọn

# YE IRAWỌ RE WO

AQURAIUS (Jan. 21-Feb 19) Oju ire ati Oju iyi ni gbogbo enia fi nwo ọ, o dara, o si tọ ki a ma ri ọrọ rere gbọ lẹnu re.

PISCES (Feb 20-Mar 20) Ọjọ oni lo dara ki iyawo rẹ lọ ra ọja onjẹ tabi awọn nkan miran lati ọja wa sile, ṣanu fun ọrẹ rẹ kan ti o fẹ lati ya owo lọwọ rẹ ran a lọwọ,

ARIES (Mar 21-April 20) Ipade aladun kan mbẹ fun o loni iṣẹ rẹ yio si ma lo daradara,

TAURIUS (April 21-May 22) Ida wo kan ti o fẹ ṣe pẹlu ọrẹ rẹ kan yio yọri si rere pe kan ti nwọn o si pe ọ ni asalẹ oni yio mu ire daniju bi o ti ro lọ.

GEMINI May 23-June 21) Eri owo kan ti o jẹ, yio pẹ ki o to ri owo na gba eyi le fa enia si iranti ede koyede kan ri a ti ba ara ani ṣe lọjọ pipẹ sẹhin wa.

CANCER (June 22-July 22) Ṣọra nipa bi o ti ṣe nna owo, fi ẹsẹ rẹ le oju ọna ti o tọ, nipa inawo maṣe jẹ ọmọ oninakuna.

LEO (July 23-Aug 22) Ko nṣe ohun ti o ṣoro bi ọlọmu ba da ọmu iya rẹ gbe, ṣugbọn ajọṣe nyin li alẹ oni yio mu ayọ faaji dani.

VIRGO (Aug 23- Sept 22) Bi ọrọ ba di ọrọ owo nina, nṣe ni ki o yara ju ara silẹ Bi o ba si gba imọran ti ẹlomiran ọ ti rẹ yio ṣe iranlọwọ fun ọ jọjọ,

LIBRA (Sept 23-Oct 23) Gbogbo eto daradara ti o ti ṣe silẹ nipa iṣẹ rẹ fẹ daru, Ki o mura lati yi goo gbo rẹ pada.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Ko si ijọngbọn kan loju ọ a, nṣe ni ki o rin tọ awọn ẹgbe rẹ lọ

SAGITTARIUS (Nov 23-Dce 21) Ohun kohun ti o ba de, maṣe mọ ọ si ohun kan ṣoikan wa ti o nfi ojire wọọ ni gbakugba.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 20) O le ṣe awọn atunṣe ti o ti wa lọkan rẹ lati ṣe ti o si mọlara koko yala sọdọ iyawo rẹ tabi ọrẹ rẹ, sa ṣe atunṣe.


...ERE BẸWO!!




## PORAL

Bi amodi "IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o nyọ ẹ lẹnu on akan bi odun kan tabi ju lẹ lo awọn egbogi rọ irọbi fun le se iwosan rẹ rara, ma fi owo rẹ se owo ofo mọ.

Bere fun egbogi awọn ara, ilu Faranse ti wọn npe ni PORAL ojulowo hanunhanun, a amatase egbogi fun Iko otutu, Ikọ ọna ọfun, Ikọ Igbaaya, Ikọ iil, Ikọ ti o ma mu enia tu kẹ ẹbẹ nigbakugba lati inu "Ifun wa (Lungs tabi ti o ba nmu enia ru pẹlu.

Bi o ba ran Igo kan PORAL yi wa Iwọ na yio ri iya tọ ninu ara rẹ ni kiakia Igbaaya tabi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro "IKỌ" rẹ yio si san ni patapata iwọ yio ma jẹun daradara iwọ yio si un fọnfọn pẹlu alafia de.

Bere egbogi yi ni awọn orisiri i Ebb gi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:—

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos
WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone:- 2287 Nigeria, (Ọjalta Faji) .... ....
Adedun Chemist
14, Weakman Street, Yaba

## MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING
*Firms Patroise* MODUPE PRESS
*Because Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs —*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupe Printing Press**

**16 Bamgbose Street**
Phone 21985, Lagos

# Ayọrunbọ Ati Panpa-laso (Apa Kẹrin)

Lati Oju Ewe Keji

rẹ lo nigbe, nwọn fi jẹ oye Balogun

Oloye keji nje Ẹgbẹji, ọkunrin yi jẹ ologun, ko mọ ohun rere, afi buburu, ṣanpọna ni o nsin, nigbamiran bi ko tori ṣe dada, ohun ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ a dide ni ọganjọ oru, nwọn a a da Ṣọpọnnaside onile kini, ki oto to ọjọ kẹta, Ṣọpọnna a bẹrẹ si ja, Odi ki Ọba gbe agogo sita, pe ẹnikan ko gbọdọ jade titi ọjọ mẹta afi ti nwọn ba ṣe Etutu tan. On gan na ni Adifa ilu, On si lo nṣe etutu, nipa bayi, gbogbo Ẹran apadari ati owo ti nwọn ba fi ṣe etutu yio jẹ tirẹ eyi mu ki awọn ilu ma fi ti bẹru tibẹru balọpọ, Ayunọrunbọ papa ti mọ pe akọni enia ni iṣe O ṣe fi jẹ Otun. Oloye kẹta nje Arom sodu Ọkunrin yi jẹ Akeweje, ẹnu rẹ to lẹ ni ilu, osi jẹ gbajumọ enia, gbogbo ilu ni ogbọ ọrọ si lẹnu Ayunọrunbọ papa mọ pe ti on ko ba fa iru enia bayi mọra ọwọ ko ni pẹ tẹ on. O fi jẹ osi Laseko ijọba Ayunọrunbọ ilu rẹ o, Ọja ta, ọmọ araiye ko ẹ gun, ko sitẹ sibẹ sibẹ gbogbo ọmọ ẹhin Ọba ti Ayunọrunbọ le kuro lori oye ko jawọ nipa ọtẹ didi abẹlẹ, nigbati ọtẹ na de oju rẹ ganna ẹnikẹni ninu wọn ko bere Ọba mọ, bi oyọ lọkan, nwọn ki iṣe ka biyesi fun mọ. Ayunọrunbọ kọ tete fiye sara, Ọtẹ yigbilẹ to bẹ ge, ti o fi jẹ wipe awọn ẹmẹwa rẹ papa Ṣọpọna pẹlu awọn ẹlọtẹ wọn yi. Ọdun ogun ko. awọn lọdọdun, orişirişi enia lowa na wọn ṣe ajọyọ ọdun ogun Ọba gunwo, onwa bi awọn Ọdẹ ti npidan orişirişi Şugbọn ohun ti o je iyalẹnu fun nipa, ko si enikan ninu ẹwọn ara ilu ti o wa yilẹ fun rabi to yẹ si, ẹyi jẹki ara fun, epe awọn ẹmẹwa rẹ, oni "ẹnyin oloye

Nwọn ko tilẹ bikita lati gburo rẹ Oli ibinu dide iu.a oni atoto arere ateto arere gbogbo won dakẹ wẹ Ọpọlọpọ ikon sinu pe ẹjẹki asare wa lo jare kiai oni lẹnu lati so Ọba tun wipe Şinu gbogbo rẹ tun dake wẹ

### AYUNỌRUNBỌ BẸRẸ SI ỌRỌ

Ohun pataki timo ni ba nyin sọ loni kopọ bogbo yin patapata gba lati oke de le koto ọsiusin loju mi mo sile pa gbo gbo yin ni isẹju kao Ọlọrun pa papa o lẹda ẹma sanu rẹ

Nioridi eyi ni mo ṣe fẹ fi oju fo nisişẹ nyin, ẹnyin okugbẹ ẹlori kunkun alaimore abar, moreje ẹkọ Ọlọrun ẹni ami olosi enia yi ki ẹ to rọ mi loye, ẹnu fun aran mi yio fi oye yin silẹ fun yin, şugbọn ẹ tete ki ẹ gbọ dada, lẹhin ti mo ba lọ ẹ o jẹ Okoto iya ti ẹ o ni gbagbe lailai, Ẹnyin Olufẹ od gba o. Gbogbo ilu pa lọ lọ.

### IROHIN AJO LỌ SI ILU ỌRUN

Ayunọrunbọ ati awọn Adeja tẹ lee, o dọrun alakeji. Ayunọrunbọ duro larin wọn, o ni Asiko to, mo npada lọ si ilu ni Ọrun alakeji, mo nlọ gba agbara kun agbara, mo nlọ gba imọ kun imọ, ọjọ nbọ ti ngo pada wa nitu ọla nla mi, ẹo ni ku, ẹ o ni run, eweko ati igi igbẹ papa yio ma şe Kabiyesi fun mi, oju yin yio ri i.

Bi o ti nsọrọ, ni Osumare ta yi ka ibiti o duro o si bẹrẹ, okun kan tinrin tin ti ọrun wa, o kan gbọ-Ayunọrunbọ di i mu, bi ere bi awada, ẹsẹ rẹ ntan nilẹ fu nigbati awọn olufẹ rẹ ri pe o nlọ, ọkan nijẹ wọn rọ mọ daniı eleyi dirọ mọ eyiu o so mọ Ayunọrunbọ bẹni gbogbo wọn ndi Ayunọrunbọ ko tilẹ mọ pe wọn so mọ on. Işeju aya, okun yi ngbe wọn lọ dẹ i, dẹgi titi wọn fi poora mọ gbogbo wọn loju. Awọn ilu eri Ẹru ko ni gbagbe ọdun ti Ayunọrunbọ ati awọn olufẹ rẹ gba ọrun lọ ojo ko kan pinrin lati oju sanma gbogbo ohun ọgbin gbẹ patapata ẹran bẹrẹsi ku, oku ọmọ wẹwẹwẹ ko ni ye nwọn şe etutu titi etutu ko gba.

Nigbayi gan ni nwọn to sọ Ayunọrunbọ dorişa, wọn sami si apa osẹ rẹ, nwọn si nbọ ni ọrọọrun. Ọjọ keje gbako ni nwọn fi dirọ mọ okun yi, ki nwọn to de agbedemeji ọrun pẹẹ ti Ayunọrunbọ ju okun silẹ, o poora mọ wọn loju awọn ọrẹ rẹ wọnyi wa wa ni agbedemeji ọrun ati aiye nwọn nrọ dirodiro wọn wa ni iru ipo bayi fun ọjọ meje gbako

IYOKU DI ỌLA


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING
*Firms Patroise* MODUPE PRESS
*Becuase Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs —*
Just Call 21985 – Leave the rest to Modupe

We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupe Printing Press**

**16 Bamgbose Street**
Phone. 21985, Lagos



HELLO ! HELLO !! HELLO !!!

**OLUSHI SOCIALISTS**

PRESENTS

FIRST ANNIVERSARY DANCE

**at Foresters Centenary Hall**
22, Odunlami Street Lagos

ON FRIDAY, 21st AUGUST, 1964, AT 6 p. m. till dawn

*MUSIC BY*

**New Time Enterprises Bashy & His Young Stars Orchestra**

Ladies and Gents, dont be told of what happen at Foresters on that 21st August 1964, how Bashy will give you many latest hits and how New Time will give you many hits of Roy Chicago, Eddie Okonta, I. K. Dairo & Broadway Dance Band Arom Ghana. Bashy is asuring you to bring along your Termogene or Mentholatum to rub your body after closing.

COME THERE IN TIME TO AVOID RUSHING

**Bar Bar Inexhaustible**

**Tickets 3s Flat**

Tickets obtainable at 16, Bamgbose Street Lagos (Irohin Imole Office) and at 3, Olushi Street Lagos

IROHIN IMOLE

IMOLE ORE AIYE. TENI GROGRO LAWA

No. 761. TUESDAY, AUGUST 4 1964 (2D)

## Ęgbę Afęnifęre Sǫ Pe Irǫ Ni Ǫrǫ Ti Chike Obi Sǫ

IBADAN:- awǫn ęgbę Afęnifęre ti ile Naijiria sǫ jade lati da esi ǫrǫ ti Dokita Chike Obi sǫ ni ǫjǫ Bǫǫi ięe ęgbęnjǫ osu to ǫja ati pe ǫrǫ ti Dǫkita Chike Obi sǫ pe irǫ patapata ni ǫrǫ na pe idi rę ti ęgbę Afęnifęre ati ęgbę Alakukǫ fę jijo fę papǫ ni pe ki Ǫlǫla Dokita Azikiwe le di Arę ilę Naijiria ati gęgębi Oloye Obafęmi Awolowo yio şe di Alakoso Ijǫba apapǫ Naijiria ati igbakeji Arę ile Naijiria ti ęgbę Afęnifęre ati Alakuko ba le bori ni asiko idibo si ile igbimǫ aso-fin ti apapǫ Ijǫba Naijiria,

Ninu ǫsę to kǫja ni olori ęgbę Dynamic Party ti o ję alabaşepǫ ęgbę olopę tęlę Dokita Obi nsǫ ninu irohin rę pe ajumǫşepǫ ęgbę on ati ęgbę Afęnifęre ti baję nitoripe ęgbę Afęnifęre ati ęgbę Alakuko si fi papǫ ati pe idi ipapǫ wǫn ni lati lo ję ki oloye Awolǫwǫ di igba keji Dokita Azikiwe ti yio wa gęgę arę ile Naijiria pelu agbara to pǫ

Ninu ǫrǫ wǫn ęgbę Afęnifęre ni ilu Ibadan ni ǫjǫ isęgun ti işe ǫjǫ keji osu yi ni awǫn ęgbę nako ghimǫ awǫn nkan ti Dǫkita Obi lori adehun ajumǫşepǫ wǫn pęlu ęgbę alakuko

## Iyaafin Awolǫwǫ Sǫ Pe:

# NWǪN ŞE ITǪJU AWOLǪWǪ DADA LǪGBA ĘWǪN

ABA:- Oloye iya afin Hannah Awolǫwǫ iyawo olori ęgbę Afęnifęre Oloye Ǫbafęmi Awolǫwǫ ti Ijǫba gbe kuro l'ǫgba ęwǫn Ikoyi l'Eko lǫ si ǫgba ęwǫn Kalaba lati lǫ şe ęwǫn ǫdun męwa ni ǫjǫ kęsan oşu to kǫja nigbati ile ęjǫ giga julǫ kǫ ębę ęwǫn ǫdun męwa ti ile ęjǫ kekere gbe si ni ǫjǫ kǫkanla oşu kęsan ǫdun 1963.

Oloye Iya afin Awolǫwǫ sǫ irǫ patapata ni irohin kan ti iwe irohin kǫ jade laipę yi pe Oloye Awolǫwǫ kǫ lati jęun l'ǫgba ęwǫn.

Iyaafin Awo sǫ fun awǫn oniwe irohin ni ilu Aba ni ipinlę Ila Orun Naijiria pe irǫ patapata ni iwe irohin na pa pe oloye Awolǫwǫ kǫ latijęun nigbati Alakoso eto ǫgba ęwǫn ilu Kalaba ko fun Dokita Oloye Awolǫwǫ l'aye lati lǫ ri Oloye Awolǫwǫ ni ǫgba ęwǫn ni ilu Kalaba.

Oloye Iya afin Hannah Awolǫwǫ tun fi ye awǫn oniwe irohin nigbati nwǫn nbere ǫrǫ l'ǫwǫ rę nigbati Iyaafin Oloye Awo de si ilu Aba lati Kalaba nibi ti o ti lǫ şe ibęwo ibilę rę Oloye Ǫbafęmi Awolǫwǫ ni o ti fi nye awǫn oniwe irohin pe ko si nkankan to şe Oloye Awolǫwǫ ati pe ara si le dada,

Oloye Iyaafin Awolǫwǫ tun fi ye awǫn oniwe irohin pe nigbati on de ǫgba ęwǫn ti ilu Kalaba lati şe ibęwo Bale on pe on ri daju pe nwǫn şe itǫju Oloye Awolǫwǫ dada ati pe itǫju ti Alakoso eto ǫgba ęwǫn fun Bale on si tę on lǫrun pupǫ ati pe Oloye Awolǫwǫ si wa dada pe ko ko si nkankan to şe rara.

Siwaju Oloye Iyaafin Hannah Awolǫwǫ tun şe alaye pe Oloye Awolǫwǫ si wa ninu ilera to ati eyi to ye ati pe ko si ohun kankan to fi ǫwǫ rin lara, Oloye Iyaafin Awolǫwǫ tun sǫ pe ko si ǫrǫ irohun kankan to ba Oloye Awolǫwǫ ati pe inu rę si dun pupǫ.



Iyaafin (Oloye) H I D Awolǫwǫ

Nigbati awǫn oniwe irohin tun fi ǫrǫ njomi turo ǫrǫ lęnu Oloye, Iyaafin Awolǫwǫ pe nję Oloye Awolǫwǫ sǫ fun pe ko si itęlorun fun ninu ǫgba ęwǫn na? Iyaafin, Oloye Awolǫwǫ si da awǫn oniwe irohin lohun pe ko si nkankan ti ko tę Oloye Awolǫwǫ lǫrun ninu ǫgba ęwǫn na ati pe Alakoso eto ǫgba ęwǫn ti Kalaba si şe itǫju Oloye Awolǫwǫ dada ati pe ko si ohun ti ko tę Oloye Awolǫwǫ lorun ninu ǫgba ęwǫn ilu Kalaba Oloye Iyaafin Awolǫwǫ tun sǫ pe on ri pe itǫju to tǫna ni nwǫn fun Oloye Awolǫwǫ.

Nigbati awǫn oniwe Irohin nbere lǫwǫ Oloye Iya afin Awolǫwǫ pe nję yio fi Orukǫ silę lati dibo si ile Igbimǫ Asofin ti apapǫ Ijǫba ilę Naijiria eyiti nwǫn yio şe Idibo rę ninu ipari Ǫdun yi ati pe yio fi orukǫ silę lati rǫpo Bale rę Oloye Ǫbafęmi Awolǫwǫ?

Oloye iya afin Awolǫwǫ si da awǫn oniwe Irohin l'ohun pe ki nwǫn si şe suru dię na ati pe ki nwǫn ję ki odi asiko ti nwǫn yio bęrę si fi Orukǫ awǫn ti yio dibo si ile Igbimǫ asofin ti apapǫ Ijǫba ilę Naijiria eyiti nwǫn yio şe Idibo rę laipę yi. Nigbati Oloye Iya afin Awolǫwǫ nba awǫn ǫmǫ ęgbę Afęnifere ni i ęyę ekini ku abǫ ti awǫn ǫmǫ ęgbę na şe fun nigbati Oloye Iya afin Awolǫwǫ de si ilu Aba ni Oloye Iya afin Awolǫwǫ si nfesi si eye ikini ku abǫ na pe ki awǫn ǫmǫ Ęgbę Afęnifęrę ati Alakukǫ papǫ dibo apapǫ, ki ęgbę mejeji le papǫ şe Ijǫba apapǫ lęhin Ibo wa

Printed and Published by Modupe Printing Press 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985
Editor: TUNJI ADEǪSUN 45, Campbell Street Lagos 4/8/64.